ÌROHIN ÌMỌLẸ

ÌMỌLẸ , ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,579 TUESDAY DECEMBER 7, 1965 (2D)

## Awon Ẹhanna Omo Ẹgbẹ Oṣelu Gb'ogun Ti Awon Ẹlẹmu !

IBADAN:— Ọrọ di pẹẹntuka, gbogbo adugbo si gbojikan fun ariwo nigbati awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu kan sare wọ inu isọ awọn Ẹlẹmu lọ ti nwọn si bẹrẹsi lu gbogbo awọn enia ti nwọn ngmu ẹmu ninu isọ wọn ni ojọ Ẹti ti iṣe ojọ kẹta oṣu yi ni adugbo kan ti nwọn npe ni Ọja Igbo.

Irohin awọn Ọlọpa Ibadan fi ye wa wipe, awọn enia na sare lọ de ọna de gbogbo awọn ọmọ ẹlẹmu ti nwọn nti eko ẹmu bọ ni ọsan ana, o si fẹrẹ jẹ wipe yika gbogbo igboro ilu Ibadan ni nwọn ti bẹrẹsi ṣe iru iṣẹ bẹ.

A tun gbọ pẹlu wipe, nigbati awọn ọmọkunrin Ibo ti nwọn nta ẹmu, ni Ibadan ba nbọ lati oko ẹmu wọn nibiti nwọn gbe lọ da ẹmu, ni awọn ẹhann ọmọ ẹgbẹ Oṣelu na yio ba lọ duro si inu igbo de wọn ni oju ọna nigbati awọn ọmọ Ibo na ba ti da ẹmu wọn tan.

Bi nwọn ba si ti ṣe de ọdọ wọn, ni awọn ẹhanna enia na yio ba sare jade ninu igbo ti nwọn sa pamọ si, nwọn

WO OJU EWE KẸFA

## Ọrọ Ile Igbimọ Aṣofin Kan Tun Kuro Ninu Dẹmọ

# ỌDUNRUN ỌMỌ ẸGBẸ DẸMỌ PADA SINU UPGA

ADO—EKITI:— Ni ojọ Aje ti iṣe ojọ kẹfa oṣu yi ni agbayanu irohin kan tun de ile iṣẹ wa lati ilu Ado-Ekiti pe ọkan ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ Dẹmọ ti nwọn ṣẹṣẹ yan sinu Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ninu idibo to da rudurudu sile ni Ipinlẹ na lọjọ kọkanla Oṣu kewa ọdun yi ti nwọn binu kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) pada sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre eyiti iṣe ọkan ninu ẹgbẹ ajamọṣepọ UPGA.

Ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ na ti o tun jẹ Aṣoju fun Otun-Ekiti ninu Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ na Ọgbẹni Edward Ojo Abe si tun ṣe alaye ninu iwe ti o fi binu kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ pe on ti binu y'ọwọ y'ẹsẹ on ninu ẹgbẹ Dẹmọ ati pe on si pada sinu ẹgbẹ on tẹlẹ eyiti iṣe ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ilẹ Naijiria.

Ọgbẹni Edward Ojo Abe ni ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti o bori ibo ni agbegbe Otun - Ekiti eyiti iṣe agbegbe kẹrinla ninu awọn agbegbe ibiti nwọn ti dibo to koja lọ yi.

Ninu iwe ti Ọgbẹni Abe fi binu kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) eyiti o kọ fi ranṣẹ si olori ẹgbẹ na Oloye Samuel Ladoke Akintọla ni o ti ṣe alaye pe on binu fi ẹgbẹ Dẹmọ silẹ lori ọrọ lati ẹnu awọn enia on ti nwọn si jẹ ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre eyiti o ṣe alaye pe on si tun pada lẹkan si tun jẹ ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre nisisiyi.

Ninu iwe ti Ọgbẹni Abe fi binu fi ẹgbẹ Dẹmọ silẹ ti o di ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni O tun kọ iru iwe kanna eyi ti iṣe ẹda iwe iwe na si Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre Alhaji D. S Adegbenro ati Alaga Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lori pe on ti kuro ninu ẹgbẹ Ọlọwọ ti on si ti pada sinu ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Ninu irohin ti a tun ti gbọ lati ilu Ilishan ni ẹkun Ijẹbu Rẹmọ eyiti Ọgbẹni Ọnafusi ti o jẹ ọkan ninu Aṣoju ninu Ile Igbimọ ti Ijọba ibilẹ ilu Ilisha pe on kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ ati pe on si pada si ẹgbẹ Afẹnifẹre Ọgbẹni Ọnafusi tun binu fi aye rẹ silẹ gẹgẹbi Ọmọ Ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Ilishan

Ninu iwe ti Ọgbẹni Ọnafusi ko ranṣẹ si Akọwe ti Ijọba nilẹ na ni oti ṣe alaye pe on binu kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ ati pe on si fi ipo on silẹ gẹgẹbi ọmọ Ilẹ Igbimọ Ijọba ibile ilu Ilishin. O tun ṣe pe idi rẹ ti on fi binu kuro ninu egbe Demi ona jibiti ati iwa mudaru ti egbe na ṣe lasikb idibo si Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba ipidle Iwọ Orun Naijiria eyiti nwọn di ibi re ni ojo kọkanla oṣu kewa ọdun yi.

Bakanna ni Ago-Iwoye ni ẹkun Ijebu ni irohin tun de ile iṣe wa pe Olori egbe Demo (NNDP) ni ilu na Ọgbẹni J. O Ogungbe tun binu fi egbe Demo sile ati pe o si ti pada sinu egbe Itesiwaju UPGA.

Ninu iwe ti Ọgbẹni J. O. Ogungbe ti iṣe Olori ẹgbẹ Dẹmọ ni ilu Agọ-Iwoye fi kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ ti o pin fun awọn oniwe irohin ni o ti ṣe alaye ninu iwe na pe on ti o jẹ olori ẹgbẹ Dẹmọ ati awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ti nwọn to ọdunrun (300) ni Ago-Iwoye ti binu kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ati pe awọn si ti di ọmọ ẹgbẹ Itẹsiwaju (UPGA).

Ọgbẹni Ogungbe tun se alaye ninu iwe ti nwọn fi kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ pe o jẹ ohunti o da on loju pe ko si ire kankan fun ẹnikẹni bikoṣe wipe ti ara wọn ni kan ni nwọn nja fun.

Ọgbẹni Ogungbe tun ṣe alaye pe eleyi ti fi han gbangba pe ko si ire kankan ti ẹgbẹ Dẹmọ si le ṣe fun awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) na tun se alaye pe ohunti o tun da awọn loju

WO OJU EWE KẸFA

## Ọlọla Branko Bẹ Oloye Ogunsanya Wo

EKO:- Ni opin ọsẹ ti o kọja lọ yi ni Ọlọla Dọkita Branko Karapandza, ẹniti iṣe Aṣoju Ijọba Orilẹ ede Yugoslavia ni Naijiria ṣe abẹwo ranpẹ kan lọ si Ile-Iṣẹ Oloye Adeniran Ogunsanya, Minista Alamojuto eto Ilẹ-wiwọn ati Ile gbigbe fun Apapọ Ijọba Naijiria lati fi ọrọ jomitoro ọrọ pẹlu ara wọn.



Aworan oke yi ni ti igbati Ọlọla Branko Karapandza ndagbere fun Oloye Adeniran Ogunsanya lẹhinti awọn mejeji ti ba ara wọn sọrọ tan.

Oniwe Irohin wa Ejongboro ti o lọ si ibiti nwọn gbe ti ṣe ibẹwo na ṣe alaye fun wa pe, ni deede agogo mẹwa owurọ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni Ọlọla Dọkita Branko Karapandza ṣe abẹwo Ile-Iṣẹ Minista na.

Ninu iforọwe ọrọ awọn mejeji, Ọlọla Branko ṣe alaye fun Oloye Ogunsanya wipe, Ijọba on ti ṣetan lati ya Orilẹ ede Naijiria, ni adoje ọkẹ pọnun (£3,600 600) fun eto idagbasoke ati ilọsiwaju.

Si idahun si ibere kan Ọlọla Branko sọ wipe ki iṣe Orilẹ ede Naijiria nikan lo ni oke iṣoro ile gbigbe fun awọn oṣiṣe. O ṣe alikun pẹlu ninu ọrọ re fun Minista na wipe, iru eyiti o ti wa fun Orilẹ-ede Yugoslavia ri.

Ṣugbọn ninu aisimi ati laala, oke iṣoro aiko ri ile gbe fun awọn Oṣiṣẹ ni ilu Yugoslavia ti di pẹtẹlẹ, Ijọba si ti pese ile olowo pọọku pọọku fun awọn Oṣiṣe.

Ni ipari ọrọ re Ọlọla Branko sọ wipe, inu on yio dun lọpọlọpọ bi Oloye Adeniran Ogunsanya ba le ṣe ibẹwo lọ si Orilẹ - ede Yugoslavia ki o si le fi oju ararẹ ri iru ile ti Ijọba on kọ fun awọn Oṣiṣẹ.

Minista na dupẹ pupọ lọwọ Aṣoju Ijọba na o si wa ṣe ileri lati ṣe ibẹwo lọ si Orilẹ ede won laipẹyi awọn mejeji si ti ayọ tuka,

## Dokita Okpara Sọ Pe ;

# ỌJỌ ITIJU ATI ẸLEYA NÍ ỌJỌ IBO IWỌ ORUN

LNUGUN: Ninu ọrọ kan to jade lati ẹnu Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila orun Naijiria ati Olori ẹgbẹ Alakoko Dọkita Michael Okpara ni o ti ṣe alaye pe ọjọ kọkanla oṣu kẹwa ọdun yi yio je ọjọ ti nwọn ki yio gbagbe ni orile ede agbaiye ati pe oju itiju ati ẹlẹya ni ọjọ na tun jọ loju awọn enia orile agbaiye lori ọna ti nwọn gba ṣe iduro na.

Dọkita Okpara nsọ eyi lati fi pari ọrọ ninu ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria eyiti o fi kesi Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria Alhaji Abubakar Tafawa Balewa lati lo agbara rẹ gẹgẹbi Alakoso apapọ Ijọba Naijiria lori ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria bayi. Dọkita Michael Okpara tun ṣe alaye pe elevi yio jẹ ọrọ alamọ kan pe lati ma a gbọ lẹnu awọn enia kan pe ohunti o ṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria je ohun o jẹ pe lati ẹhin odi Ipinlẹ Iwọ Orun lo ti wa ati pe ki oṣe lati ọwọ awọn enia Ipinlẹ na.

O tun ṣe alaye pe ti enia ba jẹ ọlọgbọn ati Oloye enia o ni ohunti o tọ ti o yẹ lati mọ pe wa jibiti tabi ẹru ti ẹgbe Dẹmọ fẹ fi ṣe eto akoso Ijọba eyiti awọn enia Ipinlẹ na ko fẹ wọn lati ṣe akoso Ijọba lo nfa rogbodiyan si Ipinlẹ Iwọ Orun bayi.

Dokita Okpara tun ṣe alaye pe nigbati ẹgbe Dẹmọ eyiti Oloye S. L. Akintola nṣe nṣe olori rẹ fẹ fi ṣe eto akoso Ijọba lọna eru eyiti awọn Adibo Ipinlẹ na ko dibo yan awọn ẹgbẹ lo fi mu ki awọn enia Ipinle na taku pe awọn ko fẹ oloye S. L. Akintola ati ẹgbẹ rẹ eyiti iṣe Dẹmọ (NNDPj

Dokita Okpara tun ṣe alaye pe lati igbati awọn enia Ipinle Iwọ Orun Naijiria ti sọ olori wọn nu ti awọn ko ti ri mọ ni eto alafia, Ijọba rere, il siwaju ati iṣọkan ti a nri ni Ipinlẹ na pelu ti o tun ṣe alaye pe lati asiko idibo si Ile Igbimo asofin ti apapọ Ijọba ni eto isọkan ati alafia ti sonu ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

O tun ṣe alaye siwaju si pe yio je ohunti ko tona lati fi a'eebu ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria



Dokita M. I. Okpara

ma kan awọn ọmọ Ile Igbimọ Asofin ati pe o tun kesi awọn Adajọ ni jakejado orilẹ ede ilẹ Naijiria lati ṣe eto idajọ wọn lọna to tọ ati eyiti o yẹ lori rogbodiyan to nṣẹlẹ ni orilẹ ede Naijiria bayi.

Ẹniti o mu aaba na jade ni ọgbẹni G. C. Okeya Balogun Ile Igbimọ Asofin Ijọba Ipinlẹ Ila Orun eyiti awọn ọmọ Ile Igbimọ na mẹta si fi ara mọ pe ki Alakoso apapọ Ijọba ilẹ Naijiria lo ipinlẹ rere lati tete ṣeki eto alafia ati Ijọba rere le padabọ si Ipinlẹ Iwọ Orun.

Ọgbẹni Okoya tun ṣe alaye ninu ọrọ rẹ pe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria Dọkita Michael Okpara ti gbiyanju eyiti o le ṣe lọkan ara rẹ lori ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinl Iwọ Orun Naijiria eyiti o je wipe o le tete lọ si opin.

Ọgbẹni G C Okeya tun bu ẹnu atẹlu ọna eru ti ẹgbẹ Dẹmọ gba ṣe eto ibo Ipinlẹ Iwọ Orun ati pe ẹgbẹ na si ba eto ofin rere ti ile Naijiria je lori eto ibo Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti nwọn ba ṣe ti ko ba eto ofin ibo lọ ti nwọn si ṣe ni ọna jibiti.

Ọgbeni Okeya tun ṣe a'aye ninu ọrọ rẹ pe o jẹ ohunti o buru pupọ lati ri enia kan ti o fẹ ba eto alafia ti Ijọba rere ti o yẹ ki o wa ni orilẹ ede Naijiria yi jẹ ati pe lati le mu wa ọna bi yio ti ṣe le ma da rogbodiyan silẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Ninu ẹniti o tun fi ara mọ aaba na Ọgbẹni Okoya fi silẹ ra ni Ogon eyiti o mu ẹnu ba ọrọ Ologbe Wiston Churchill ti iṣe alakoso Ijọba ilẹ Gẹẹsi tẹlẹ ati pe o si tun ṣe alaye pe ohunti o nṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwo Orun bayi ti kuro lọrọ eto ọrọ Iṣel.

O tun kesi Alakoso apapọ Ijọba Naijiria lati ri pe eto alafia si pada si Ipinlẹ na ati pe ki o si ri pe idanilo u si wa pe ki yio si pe awọn enia kan yio fi iya ma jẹ awọn Ẹlomiran lori eto ọrọ iṣelu.

Ọgbẹni Ogon tun se alaye pe ohunti o to ti o si ye alakoso apapo Ijoba Naijiria ni lati mura bayi ki o fi eto ọra iselu sile ki osi se ona bi nwon yio ti se eto ofin kan lori ile Naijiria eyiti awon enia kan fẹ fi eto oro oselu bajẹ bayi ati pe ki nwon ri si le se eto bi rogbodiyan paapa julo ni Ipinle Ile Iwo orun Naijiria le lo si lẹ

Ọgbeni Ogon tun se ala ye ki Alakoso apapọ Ijoba Naijiria pe ipade kan eyiti yio jẹ ti gbogbo awon Asoju omo egbe oselu lati lẹ je ki iwa buburu ti o nsẹle yi le tete lo si opin ati pe ki nwon si jeki gbogbo ohun ti nwon bi rse mu lo ni na eto ofin la si jwa madaru tabi ona jibiti ni ile Naijira

Ninu eniti o tun soro ninu awon ọmọ ile Igbimo Asofin Ijoba Ila orun na ni Dokita Chike obi olori ẹge Dynamic Part ati Asoju iha Ariwa si ila orun ilu Onitsha ninu ile Igbimo na o se alaye pe eto ofin rere si nsi aisan ile Naijiria ati pe ko ko si eto ofin rere ni ile Naijiri bayi

Dokita Chike Obi tun ke si awon omo ile Igbimo Asofin Ijoba Ipinlẹ na lati ke owo osu won ati awon oloye ki si gegebi oti se wa tele

# Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

## Mo Ki Awọn Adibo Eko

Kosi eniti yio gbọ abayori ibo ti nwọn di ni ilu Eko ni opin osu ti o koja yi ti inu rẹ ko ni dun pupọ fun ọna ti nwọn fi dibo na fun ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o fi jẹ wipe, awọn ni o ko aye ti o joju ninu awọn aye na.

Eyiti o ya enia lẹnu ninu ibo ti nwọn di na ni ti awọn ti o fẹ ba ibo ẹgbẹ Afẹnifẹre jẹ ti nwọn ni ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ko faramọ ẹgbẹ na mọ. Bi awọn enia na kọsẹ wọle jẹ idunnu fun gbogbo wa pe nwọn ti mọ awọn ọta ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Iwa ti awọn kan ma nhu ninu ẹgbẹ papa ẹgbẹ Afẹnifẹre ko dara to rara, nigbagbogbo ni die ninu won maa ntako awọn ti ọmọ ẹgbẹ na ba ti gbe sita lati dibo sun sra iwa yi ni o fa ti awọn ti o nwa ipo fi fẹ ba ẹgbẹ Afẹnifẹre jẹ ti Ọlọrun ko fi fun wọn ṣe.

Lẹkan si, mo tun ki ẹnyin ọmọ ati ara Eko ti ẹ fi ibinu dibo fun ẹgbẹ Afẹnifẹre, Oluwa yio jẹki ilẹ gbogbo wa turo amin.

Emi ni
Yẹkini Bello
YABA

## Mo Ba Latifu Babalola Yọ

Olotu ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe rẹ ti o kun fun ogbọn ati ove lati ba Ọgbẹni Latifu Babalọla yọ fun ọmọbinrin kan jojolo ti Ọlọrun fi ta lọrẹ ninu osẹ ti o kọja yi ki Ọlọrun ba ni di ọmọ nasi fun awọn obi rẹ ati fun ogo ilẹ Naijiria.

Bi a ti ka inu iwe Irohin Imọlẹ pe Ọgbẹni Latifu Babalọla di baba ikoko inu wa dun pupọ fun ore nla ti Ọlọrun se fun Ọgbẹni Babalọla ati Falilatu Aresao iyawo rẹ.

Mo ki awọn osisẹ iwe Irohin Imọlẹ pe ẹ ku ewu ọmọ tuntun jojolo Ọlọrun yio da ọmọ na si amin Ọlọrun yio pese ọmo rere fun gbogbo nyin o amin.

Awọn ti Ọlọrun si ti pese ọmo fun Oluwa yio wo gbogbo wọn pọ amin ati amin Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
L B Buraimọ
Eko

## Ilu Ipokia Nfẹ Itoju Ijọba

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin to kun fun ogbọn ati ove lati kesi Ijọbe Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati fete ba awa enia ilu Ipokia mu oju to ilu wa ati papa julo awọn Oju ona wa ti ko ba oju mu ati pe a si nfẹ awọn nkan miran ti yio mu ilosiwaju si ilu wa nitori pe eko mo ohunti Ijọba fi owo ori ti a nsan ṣe.

Mo ro pe o ti to ọdun meta sẹn to jẹ pe a ti nkesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati ṣe iranlọwọ yi fun wa ṣugbọn ko si eto iranlọwọ kankan ti ari gba lati igbati Ijọba na ti kuro lọwọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ko ti si ohun idagbasoke kankan ni ilu wa.

Inu awa enia ilu na yio dun bi Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ba le ṣe awọn nkan wọnyi fun awọn bi Ile Iwo san nla Ẹrọ omi Ina mọnamọna ti yio wa kakiri opopo oju ọna ilu wa ati ile ifi iwe ranṣẹ pelu.

Olotu mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi ajinde yio ma jẹ fun nyin o

Emi ni
BISI ALADE
IPOKIA

## Ijẹbu-Ode Nfẹ Papa Iṣire Boolu

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye die ninu iwe nyin to kun fun ogbọn ati ove lati kesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati Ijọba ibilẹ ti ilu Ijẹbu Ode lati ṣe iranlọwọ fun awa ọmọ ile ẹkọ ati awọn ọdọ ilu Ijẹbu Ode ti a gbe rẹ lati ko papa isire boolu si ilu Ijẹbu Ode eyiti yio jẹ iranlọwọ fun awa enia ilu na.

Eleyi jẹ ohunti o jẹ pataki pupọ lati ṣe ọtọbi nwọn yio ti ṣe ko papa Iṣire si ilu Ijẹbu Ode ati pe ki o si le dabi ti ilu miran ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọpọ lọpọ igba lo jẹ wipe o ma lewu fun wa pupọ lati le ri ibiti a ti ma n gba boolu ati pe ninu ọgba ile ẹkọ ni ilu Ijẹbu Ode ni a ti nlọ gba boolu nigbamiran eyiti o jẹ wipe ti a ba ni papa iṣere ko le dabi eleyi fun wa.

Inu wa yio dun bi awọn Igbimọ ti Ijọba ibilẹ ilu Ijẹbu Ode le ṣe iranlọwọ yi fun wa laipe yi ki nwọn si ba wa ṣe ohunti a nbere yi.

Olotu mo dupe fun aye ti ẹ gba mi, ọkọ Ọba kọ ni si nyin lẹsẹ o

Emi ni
Surajudeen Kazeem
IJẸBU—ODE


### ỌJA KO TA !

Nisiyi o, Ọja ko ta mọ, ṣugbọn ohun ti o yẹ ki ẹ ṣe ti ọja yin yio fi ma ta bi akara gbigbona ni ki ẹ polowo rẹ sinu iwe IROHIN IMỌLẸ. Iwe Irohin kanṣoṣo ti o njade l'ede Yoruba lojojumo.



# GBANJO!

NOVEMBER 15th — DECEMBER 15th 1965



Iwe itumo Ala,
Etutu Sise ise wiwo,
Ojo ibi Omo, ati
Ogun Ajebidan
3s 6d di 1s 6d

Iwe Afose Isedale
Yoruba ati Psalmu
Ajebidan.
3s 6d di 2s

Turari 2s 6d Paketi di 1/-

A le ri iwe wonyi ra lọdọ :-
SHỌYINKA ni 9, Iyalla Street, Mushin

J. O. SHOYINKA P. O. Box 159 Mushin.

# WOLI KAN JI IṢU GBE

IBADAN:— Oju gba gbogbo enia ti nigbati nwọn gbọ ninu ọrọ Ọlọpa ti o nba ọdaran kan ti o npe ara re ni Woli pe o lọ ji iṣu mẹjọ ko eyiti awọn enia ti o wa ninu ile ejọ na nsọ pe a ṣe Woli eke yio po gẹgẹbi ọrọ mimọ Ọlọrun ti wi kini o le wa sun enia Ọlọrun la ti lọ ji iṣu

Nigbati Ọlọpa ti o nba ọdaran na "Woli" James Adio ṣejo ni o ti sọ fun ile ẹjọ Ijọba ibilẹ Ibadan ni opin ọsẹ yi pe ọdaran na lọ si agbebe Jericho ni Ibadan si o ba Ọgbẹni Busari Arẹmu ti o si ji iṣu rẹ mẹjọ gbe ni ọjọ kẹfa oṣu kọkan la ọdun yi

Nigbati adajọ ile ẹjọ Ijọba ibilẹ bere lọwọ rẹ pe nje o jẹbi awọn ẹsun ti wọn ka si ọ lẹsẹ yi ? O ṣba pe nitootọ ni on lọ ji awọn iṣu na ko o wa rọ adajo pe ki o ṣanu on nitori Ọlọrun eṣu ni o ten on pitapa o ko tun ni ṣe bẹ mọ

Adajo bi on ko le ṣe anu ole nitoripe bi enia ba pe ararẹ ni ena Ọlorun o ye ki iwa rẹ le jẹ apẹrẹ re fun awon enia ti yio ma a to lẹhin o wa pari oro rẹ bayi nje bi oniwasi ba nja ole kini awon omo ijo yio wa ma ṣe ? nitorina on yio ṣe adajo fun odaran na gẹgẹbi ofin ba ti ṣe wi

Ni adajo ba ni ki Woli James lo fi ẹwon oṣu mẹfa jura pe bi o ba de ko tun ni de aṣa bẹ mo.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS(Jan 22-Feb 20): Ṣ ara rẹ g ri, ki o si ṣe bi ọkunrin maṣe jẹki amodi kan mbi aisan gbe ọ sanlẹ

PISCES(Feb 21-Mar 20): Maṣe fi ọkan si fi awọn iṣora ti o wa fun nṣe ni ki o fi ọkan si ti awọn ti o nifẹ rẹ si nwọn ṣogba yi ọ ka.

ARIES (Mar 21 April 20) Ṣọra gidigidi ki o maṣe a de lọ se ibikan loni nitori pe ewu mbẹ fun ọ nibi pupọ ṣe pẹlẹ.

TARUS (April 21 May 20)Ri o ṣota yiya enia ni owo rẹpẹt loni ṣe jẹjẹ ki o si ṣe suru ọpọlọpọ ire ni yio si silẹ niwaju rẹ.

GEMINI (May 21 June 21) Irawọ rẹ yio ni alatako loni ṣe suru ki o si dakẹ jẹjẹ ọpọlopo awon ehunti o ti ngba bi ere yio jade ni otito.

CANCER (June 22 July 22) Gbo ikilo yi maṣe jade lo si ode ni alẹ oni bẹni ki o maṣe pẹ ki o to wole lo dibulẹ ṣe gbogbo nkan iwonwonwons loni ki o ma ṣe fi iṣẹ pa ara rẹ lori.

LEO (July 24 Aug 22) Aye yio gba o ni bi kibi loni, ire lwaju ti o mbo ni ki o ma wo.

VIRGO Aug 23 Sept 23) Igba le yi pa ja tobẹ ti o fi jẹ pe gbogbo ohunti o ngba lero ni iwo yio yi pada ti i o yio si mu ọna miran pon,

LIBRA Sept 24 Oct 23) Ọrọ kekere tiko to oro kan le ko arẹ okan wa fun o ṣe suru.

SCORPIO (Oct 24 Nov 22)Bio ba di asalẹ ki o ṣe jẹjẹ ati pẹlu pẹlẹ maṣe jẹki ero olcro o dasi ki o ma ba di oro si o l ron

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Ọpọlọpọ ero ni yio dele, ero ti iwo y o ni fati da si mu rẹ ṣugbọ oro ti owo yio wa iowo rẹ yio ma o loni maṣe binu si

CAPRICORN Dec 22 Jan 21 Jẹ onjẹ ti o fẹyẹ loni bi o ba di ni awon omo wẹrẹ ni sa asi ọdọ rẹ toju won ki okan buruku kan maṣe ṣẹlẹ

BERE FUN OJULOWO ADI ELEGBO

## "Congreve's Iodo Form--Ointment'



Atamatase ni egbogi" ADI-ELEGBO" yi i fun itoju gbo gbo orisirisi "EGBO—EṢẸ" n kiakia bi o ti wun ki o jọ rẹ to le pẹ to, Adie'egbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko idọti ti bi ẹr gbogbo ti o ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lẹhinna oju egbo ti o ba jin si nu yio jẹ ki oju re ru wa soke, y o si pọn daradara fun rakaru ko si mo ae ewere ni yio si san pata pata. Alafia de si ọ niyen :

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won si isale iwe yi ni egbe ranṣe lọ ra Bibẹko awon Eleru tabi onijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba re ra o.

Bere egbogi yi ni ṣoba awon :—

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.
WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Phone 22787

## Ha! Kini eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN META NI

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile n kiakia ogun re si da ra pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tu yara pa ayan ati idọn

Tete lo ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si da wo, iwo yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta yi ni nw n mu un ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ati ile itaja kakiri orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS
AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

# OGUNẸSAN ỌMỌ ALA-PO NLA (Apa 4)

Lẹhinti Balogun ilu ti pari ọrọ .ẹ loruko gbogbo aralu o pe d ẹ ki ariwo to d kẹ nitoripe gbogbo bi Balogun ti nsadura ni ariwo Amin Amin aṣẹ ate Oluwa gbo ol wa gba ati bẹbẹl lọ gba gbogbo ilu kan dọnu lẹhin ti nwọn si dake, emi na ki wọ mọ ni iba ọba ibi baba mi Alapo nla Ogun na gbongbo larin ẹgun ọridi babara k.ado si baba ẹsan ma waju ba onilẹ alejo ọkunrin obinrin omode agba awọn on ṣẹgun ati awọn ada huuṣe alufa ati refẹrẹndi, ati gbogbo ẹniti kika mi tọ si ẹni pataki awọn iya o ṣoronga awọn iyaagba ti torijapa . awọn atẹdọ jọkan, awọn arifun joronro ọgalan ti nwọn nmumi ṣalọ

salọ ẹ jẹko yẹmi loni nitori yiyẹ nii yẹ eiyẹle riro i ro adaba lọrun A y lọ ayibọ ki pa ọlu . t a tẹ lọ a tẹbọ ki pa ọna k k ki ile ku ilẹ a ṣa ẹniti o ba ro ika ro m loni bi ẹkun bi ẹkun niṣẹ egb re bi ofo niṣe apa-ro aroju air ye ti k i jẹki alagbẹde le kolẹ aro ki o ba gbogbo awon aṣeni Ẹ nyin ene mi emi kii ṣe iro Alapo nla ti emi di

ọmọ ọba awọn ijoye ati ọmọ gbogbo arailu nitoripe Alaponla nik n k ni mo nlọ ṣe iṣẹ yi fun bi ko ṣe fun ọmọ temi tirẹ ati ti gbogbo wa Nkoni ẹrọ iso pupo ju pe mo ṣe ileri pe bi ẹ ba gbo gbii GBANKỌBI ku iatẹwọ ati ariwo so ino.

wọn si dun nitori ado ti mbẹ nile mi le ni ir nwo bẹni atọ ti mbẹ ni yara mi le iẹgbẹfa. ojule nirin-wo ondẹ, ni mbẹ ni baradi ni, Ti gbẹrẹ ti mo sin sinsin ti o kan egungun ni ki a so ni, tabi ti ogun ti mo jẹ titi ti mo nfi nyagbẹ ogun tabi ti oriṣiriṣi ofo ti o ti ni afin sibi kolopin.

agbari mi? (atẹwọ tun sọ) lẹhinna bal gun sọ wipe, odidi balogun meje ni ẹran ko yi ti pa, ṣugb n o gba-gbe pe ẹni ju ẹni lọ, eni ju enia ẹmọ ti ẹkan ta bi ko ni gbi mọ bi a ti i fa eran ya pẹrẹpẹrẹ adọse ni nhun ni, iba ko gbọdọ hun ọmọ enia, mo juba akedẹ ero, mo ti juba adigbẹhin ika, mo si ti juba obi to koro to dun ju iwọ lọ

Laeṣi ani-ani alagbarayio mọ wa ọgbọn kun ọg ọn imọ kun im ati agba-ra kun agbara, on yio si ma wa ni iwaju la lai ṣu gbọ a wọn ọlẹ ti ko jawe yanju ti ko koṣẹ yanju yio

**Lati Owo**

**Abdullah Awẹlẹjẹ**

ni tẹlọrun pẹlu ipo iya ti nwọn wa. yio ma re i owo tiko s Ẹniti ko ṣa ẹ u lọ gb ri ko ta ọ ṣurọ l fa ti o de idi ọpẹ ti o gb ko se ẹfẹ ni ma ro bi? Ọlẹ wa ibẹ n gnat al bar nṣẹ ko le yọju, ṣugbọn gb ti alagbara ba njẹ ọrọ iṣẹ ti o ti ṣe ọlẹ yio ma yọ ẹnu Ẹ u ni ọlẹ ni lasan bi eiye awoko, odo ẹniti o ba si ti nronje je ni gbenu si bi kọ ba si ri o je mọ, a bere si on toh n ba Ẹ yin ara mi e yin obinrin otito ni Oluwa ti ponmi anu si kolofin ibi oju nyin, ṣu gbon e maṣe fi ekun sin mi ki k mi mi ba wa o, nitori eyi ni nko se jẹki iya mi j de sinmi ti o duro lenu ona ile ti nsunkun kikan kikan, Nko ma lo wayi, alagbara doju kọ ke iṣoro di pẹtẹlẹ ọkan ẹ si le koko bi okuta hla inu om ṣu-gbọn eka ọlẹ enia dabi iy pẹ ti toti o ẹpe bi ba ti n ẹsẹ ka ko ṣe ko ọ ẹnyin ọmọde e gbọju ki ẹ gb iya bi i ọsi ba ta le gbọn nu kia kia iwọsi ni ki ẹtanko aiyẹ la lati lati yi ma wa yọ wa lẹnu lọdọ dun e yio pin loni ẹ fadu ra sia mi ọkunria lọ

Ibiti ba a ba ọr rẹ de ni yi ti orun k

IYOKU DI ỌLA


## Iwo Ha Nfẹ Ile LEko Bi

| | |
|---|---|
| Room | £3 10/ |
| Room | £4 |
| Room | £5 |
| Room / Parlour | £6 |
| Room / Shop | £15 |
| Flat (Lgos) | £20 |
| Flat (EB) | £25 |

Ti o ba nfẹ ọkan ninu awọn ile wọnyi yaa tete lọ ri-Ọgbẹni ODUS:— 187 Bamgboṣe Street Lagos

ni deede agogo mẹrin irọlẹ si agogo mẹfa irọlẹ. ijafara lewu anfani nla kan ni eyi jẹ fun ọ pe o ri ile l'Eko



# Kere o Kere o Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hannnhanun Egbogi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ile Naijiria

A wa na njẹwọ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe oro ati orin larin ara won nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ soya tani pe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inurirun nigbakugba ara wiwo, Ẹsanri ehin didun sisan ati aiko riran kedere ko dara buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni ki wak ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹj ṣẹ enia nipa sis d ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ORO IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile mẹfa abọ (6/-6 pere Igo kekere ṣile mẹta abo (3/6) pere/ Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Ph ne.- 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

NIGERIAN MEDICINE STORE,
4, Tinubu Square Lagos

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,579 TUESDAY DECEMBER 7, 1965 (2D)


## Adebola Lo Si Amẹrika

EKO:- Ni opin ọsẹ to kọja lọ yi ni olori ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ eyiti a npe ni "United Labour Congress of Nigeria" Alhaji Haruna Popoola Adebola ba ọkọ ofurufu filẹ Naijiria silẹ lo si ilẹ Amẹrika nibiti lọ ba wọn ṣe eto ipade kan eyiti gbogbo awọn olori ẹgbẹ oṣiṣẹ jakejado orilẹ ede agbaiye yio peṣẹ sibi ipade ti nwọn yio ṣe na.

Ohunti awọn Olori ẹgbẹ oṣiṣẹ eyiti Alhaji H. P. Adebọla yio ba nwọn ṣe ninu ipade na ti nwọn yio ṣe ipade le lori si jẹ "Eto awọn oṣiṣẹ lori idagbasoke agbaiye

Nibiti awọn olori ẹgbẹ oṣiṣẹ na yio ti ṣe ipade ti nwọn yio ṣe ni ilẹ Amẹrika na ni ile ẹkọ giga julọ ti Unifasiti ti Ipinlẹ Gusu Califonia ni ilẹ Amẹrika.

Lehinti awọn olori ẹgbẹ oṣiṣẹ na ba pari eto ipade wọn na tan ni Alhaji Adebọla yio tun lọ sibi ipade kan eyiti awọn olori ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ ti ile Amẹrika yio tun ṣe ni ibi kan Francisco nibiti nwọn yio tiṣe ipade na ni Alhaji Adebọla yio si je Asoju ninu ipade ojọ na irohin ko fi ye wa ni ọjọ ti yio pada si ile Naijiria.

# AWỌN OBINRIN ỌLỌJA KILỌ FUN IJỌBA IBILẸ

WASIMI:- Awọn Igbimọ obinrin ọlọja to wa ni ilu Wasimi lẹba Ifọ ni agbegbe Abẹokuta ni nwọn ṣe ipade alabẹṣekele kan ni opin ọsẹ to kọja yi lori iwa aidara ti awọn oṣiṣẹ Ijọba Ibilẹ Ifọ nhu si awọn obinrin ọlọja na eyi ti ko ba ofin mu rara, nwọn ni awọn nfẹ ki awọn oṣiṣẹ Ijọba Ibilẹ Ẹgba Ifọ pe, ki nwọn tete lọ fi ọwọ ọmọ nwọnbọ asọ ni asiko.

Eyi ni awọn ọrọ ti ẹgbẹ obinrin ọlọja to wa ni ibudokọ reluwe ti Wasimi kọ ranṣẹ si Ijọba ibilẹ Ẹgba Ifọ ni nwọn ni awọn fẹ ki wọn kilọ fun awọn oṣiṣẹ ki nwọn ma tun wa ma a yọ awọn lẹnu mọ ninu iso ti Ijọba ibilẹ na ko kọ fun awọn.

Nwọn ni owo ara awọn ni awọn da ni tiro kọbọ ti awọn si kọ iso na fun ara won, nwon ni bi enia ko ba le pa bo ile oriṣa ko gbọdo yo tibẹ, nigbati Ijoba ko fun awon niso ni awon ba wa woroko fi ṣe ada

Ninu iwe ti awon mefa ninu obinrin oloja na fowo si ni nwon ti tabuku Ijoba ibilẹ na, nwon ni Ijoba ibilẹ na nfonnu pe, awon ti fi owo nla silẹ lati fi tun gbogbo iso na ṣe ati lati tun awon to ti bajẹ ko ki o le ba ode oni mu.

Ṣugbon eyiti awon tun ma ri ni awon kan ti nwon npe ara won ni oṣiṣẹ Ijoba ibilẹ na pe awon fẹ gba owo iso ti awon ti nta oja nwon ni eyiti o wa buru ni bẹ ni ti awon ehanna toto mẹwa pẹlu awon oṣiṣẹ Ijoba ibilẹ na pe awon wa gba torotoro lowo awon obinrin oloja na.

Nwon wa pari oro won bayi pe ni asiko ti awon ehanna yi fi wa pẹlu ipa ati talasa ni nwon n gba owo na ti nwon si ba gbogbo oja awon jẹ ati awon iso, la ti igba na ni nwon ko ti wa tun awon iso na ṣe rara.

Awon obinrin oloja ti o fi owo si iwe ẹbẹ na ni awon iyalọfin Lagunju Ade oti Seliatu Ajiwon, Sobowale, Adeṣola ati Asia Ẹfunrunte.

## Iyawo Ọga Tun W'ẹwon Odun Meji !

IBADAN:- Oju gba gbogbo enia ti nigbati Adajọ agba ile ẹjọ kekere ti Ibadan Ọgbẹni A. O. Lapitẹ paṣẹ pe ki iyawo Alakoso Ile iṣe ti Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria Adenikẹ Ogunbiyi yara lọ fi ẹwọn ọdun meji lọ jura lori ẹsun ole jija ati pe ọdaran na tun fi ọna jibiti gba owo lọwọ Ọkunrin kan pe on fẹ ba ra mọto.

Ninu oro Ọlọpa to ba ọdaran Obinrin iyawo Alakoso ile iṣẹ Ijoba ti Ipinlẹ Iwọ Orun ni o ti ṣe alaye pe Adenikẹ Ogunbiyi lọ gba ọdunrin ponun (£300) lowo Ọgbẹni Oladejo Adedapọ ni Bodija, Ibadan ati pe on yio lọ ṣe gigun ati gẹgẹbi ipo on ninu awon oṣiṣẹ ninu ile iṣe A. G. Levent's pe on yio ba Ọgbẹni Oladẹjo Adedapọ ra mọ to ayọkẹlẹ ti nwon npe ni "Mercedes Benz" eyiti iṣe ise aloku ninu ile iṣẹ wọn.

Ọlọpa na tun ṣe alaye fun ile ẹjọ pe Obinrin onijibiti na a kan gba ọdunrin ponun (£300) lọwọ Ọgbẹni Oladẹjọ Adedapọ ko si ba ra mọto na.

Ninu oro ti Obinrin ọdaran na ey ti o fi gba ara rẹ silẹ ni o ti ṣe alaye fun ile ẹjọ pe nṣe ni Ọkunrin na Oladejo Adedapọ pa irọ nla mọ on ati wipe on ko gba owo kankan lọwọ Ọkunrin na.

Ninu idajo adajo agba ile ẹjo na ogbẹni A O Lapitẹ ti ṣe alaye pe obinrin odaran na si wa logba ẹwon bayi nibiti o a ti nṣe ẹwon oṣu mẹrin lori iru ẹsun kan na

Adajo agba ile ẹjo na tun ṣe alaye pe gbogbo oro ti olopa to ba odaran na ṣe jo ro niwaju ile ẹjo na na on si gbagbo pe ki iṣe po okunrin to fun odaran obinrin na ogbẹni Adedapọ ko pa iro kankan mo o

O tun ṣe alaye pe ko si oju anu ti on gbodo ni si iru odaran obinrin bayi ni toripe ko gbero igbesi aiye rere fun ara rẹ

Adajọ agba ile ẹjọ na si paṣẹ pe ki ọdaran obinrin na Adenikẹ Ogunbiyi yara tun lọ fi ẹwọn ọdun meji jura lori ẹsun na

Adenike Ogunbiyi ko si ba agbẹjoro kankan lati wa gbenuso fun on lori ẹsun ti nwọn mu on wa si ile ẹjọ fun

## Lati Oju Ewe Kini

yio si bẹrẹsi maa lu awọn ẹlẹmu na, nwọn yio si tun fọ gbogbo akerengbe ẹmu ti awọn so, mọ basikilu wọn ti nwọn ngbe bọ wa si igboro ilu Ibadan lati wa ta gẹgẹbi iṣẹ wọn ti nwọn nṣe.

A gbọ wipe awọn enia na ti bẹrẹsi maa sọ kaakiri wipe awọn yio le gbogbo awọn ọmọ Ibo ti nwọn nta ẹmu kuro ni igboro ilu Ibadan, ki gbogbo wọn pada lọ si ilu wọn ki nwọn ma a lọ da ẹmu nibẹ.

Irohin awọn Ọlọpa Ibadan sọ wipe awọn ko ti ri ẹnikankan mu ninu awọn ẹhanna enia ti nwọn nhu iru iwa bayi, ṣugbọn nwọn ṣe alaye fun Oniwe Irohin wa wipe awọn akerengbe ẹmu ti awọn enia na fọ ni ọjọ na le ni ogoje (150)

## Ọdunrun Ọmọ Egbẹ Dẹmo Pada

LATI OJU EWE KINI

pe ko si ohunti o mu ilọsiwoju kankan iwa ti ẹgbẹ Demo ṣe si awọn ilu to wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun lasiko ti nwọn ṣe akoso Ijọba ni Ipinlẹ na, ati pe eyi fi han pe eru ni nwọn fi eto idibo to kọja lọ yi ṣe

Awọn enia na si fi iwe ti nwọn fi bin kuro ninu ẹgbẹ Dẹmọ na ranṣẹ si Olori ẹgbẹ Dẹmọ Oloye Samuel Ladoke Akintọla.


Printed & Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 45 Campbell Street Lagos. 7/12/65